**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**OJÚ TI GBOGBO ÀWỌN Ọ̀TÁ RẸ̀**

**OṢÙ KẸTA, ỌDÚN 2024**

Ìwé Mímọ́ Kíkà: Lúkù 13

Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 40:14

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí àwọn tó nwá ọkàn mi láti parun gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá mi, jẹ́ kí gbogbo agbára búburú tó nká èso ayànmọ́ mi, jọ̀wọ́ rẹ̀, kí wọ́n sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ọjọ́ ogun, ibànújẹ́ ati ipọnju, akoko rẹ dopin ninu aye mi, ku, ní orúkọ Jésù.
8. Awọn agbara to fẹ gb'ẹmi alumọni mi, ku, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo jẹran-jẹran ati mujẹ-mujẹ, ti wọn yan lati yọ ayanmọ mi lẹnu, ku, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo irinṣẹ́ òkùnkùn tí wọ́n lò láti fi mí sí ihò ìdárungún sójúkan, gbiná, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ìrúnú tó lòdì sí ayànmọ́ mi láti ọwọ́ àwọn tó kórira ayànmọ́ mi, dópin, ní orúkọ Jésù.

12. Olúwa, fimípamọ́ sínú ẹ̀jẹ̀ Jésù lòdì sí àwọn àgbà ìkà, ní orúkọ Jésù.
13. Ẹ̀mí Mímọ́, fọ́ ojú gbogbo ẹyẹ àjẹ́ tó nwo àwọn ibùkún mi, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo ọ̀rọ̀ búburú tí ahọ́n ikú sọ lòdì sí mi, gba ìfagilé nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
15. Mo fọ́ gbogbo ègún òkùnkùn lórí mi, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ìdin t'ẹ̀mí nínú ayànmọ́ mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo iṣòro tó wọnú ayé mi láti ipàṣẹ̀ ẹ̀jẹ̀ àwọn òbí mi, kú, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo agbára tó n jijàkadì láti gbé mi mìn, ìwọ ilẹ̀, lanu, gbé wọn mìn, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo agbára òkùnkùn, tó n ṣàmì sí ojú mi fún ìparun, ìwọ ilẹ̀, gbé wọn mìn, ní orúkọ Jésù.
20. Ẹ̀gàn òkùnkùn tí wọ́n yàn láti gbé mi mìn, tapadà, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo ọfà láti ẹnu àwọn àgbà ìkà tó lòdì sí mi, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
22. Ìwọ idà nínú ètè àwọn ìkà, pa ika, ní orúkọ Jésù.
23. Àwọn agbára ogun mi tó lágbára, wólulẹ̀, kí o sì gbiná, ní orúkọ Jésù.
24. Gbogbo àṣírí agbára ìkà, tí wọ́n yàn láti fi ìwàsáyé mi ṣòfò, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
25. Ọlọ́run dìde, ṣe ìparun fún orí ọ̀tá tó dìde lòdì sí mi, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo àjọyọ̀ ìkà, tí wọ́n ṣètò láti gbé ayànmọ́ mi mìn, yípadà di ìṣínwín, ní orúkọ Jésù.
27. Àwọn agbára, tí wọ́n n dúkokò mọ́ mi láti dá ohun tí nkò gbà lọ́wọ́ wọn padà, Olúwa, lù wọ́n pa, ní orúkọ Jésù.
28. Ohun ìyówù tó n dábóbò àwọn ọ̀tá mi lòdì sí mi, di pánpẹ́ ikú fún wọn, ní orúkọ Jésù.
29. Ìrúnú ìbínú Ọlọ́run, mú òkùnkùn tó n tẹ̀lé mi kiri so, ní orúkọ Jésù.

30. Aṣọ òkùnkùn tó n ṣiṣẹ́ nínú ayànmọ́ mi, mo fà ọ́ ya sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
31. Ìwọ ọkùnrin alágbára ìrandíran, tó dúró sáàrín èmi àti ayànmọ́ mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
32. Májẹ̀mú àsopọ̀ ọkàn búburú, tó somí pọ̀mọ́ àwọn tó ti kú, fọ́ nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù.
33. Ìdádúró ayànmọ́ nínú ayé mi, tí àwọn àlá búburú ṣòkùnfà, fọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
34. Àyídáyidà ayànmọ́, pòórá kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
35. Ẹ̀yin ángẹ́lì jagunjagun Ọlọ́run Alàáyè, ẹ dìde, ẹ gbógun, kí ẹ sì ṣe ìparun fún gbogbo ángẹ́lì ibi tí wọ́n yàn lòdì sí mi, ní orúkọ Jésù.
36. Ẹ̀yin ángẹ́lì jagunjagun Ọlọ́run Alàáyè, ẹ dìde, ẹ mú gbogbo agbára tó n dúkokò mọ́ mi so, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo agbára tó nti àwọn ilẹ̀kùn rere mi pa, tí wọ́n dámidúró sórí okùn ìdárungún, kú báyì, ní orúkọ Jésù.
38. Àwọn drágónì òkùnkùn, tí wọ́n n ṣiṣẹ́ lòdì sí mi, di gbígbésin lóóyẹ̀ báyì, ní orúkọ Jésù.
39. Ọlọ́run Ṣádrákì, Méṣákì àti Àbédnégò, jẹ́ kí Nebukadnéssárì mi ṣègbé sínú iná tí ó dá fún mi, ní orúkọ Jésù.
40. Gbogbo ogun tó n bí ìjà sílẹ̀ nínú ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.